25

DEPARTMENT OF LINGUISTICS, AFRICAN & ASIAN STUDIES

FACULTY OF ARTS
UNIVERSITY OF LAGOS
AKOKA, YABA, LAGOS, NIGERIA
Tel: 01 5454891-5 Ext: 1384
Email: afriasian@unilag.edu.ng

4th May, 2017

**RE: "FÍÌMÙ ÀGBÉLÉWÒ GẸ́GẸ́ BÍ OHUN-ÈLÒ ÌKỌ́NI NÍ ÀṢÀ ÀTI LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ: *FÍÌMÙ ARUGBÁ* ÀTI *BAṢỌ̀RUN GÁÀ* GẸ́GẸ́ BÍ ÀWÒTA"**

Dear **Adéyínká, A.A. & Akínṣọlá, I.T.**
Department of Arts and Social Sciences Education
Faculty of Education,
University of Ibadan,
Ibadan, Nigeria.

We are pleased to inform you that your above-titled article has been peer-reviewed and accepted for publication for "Yorùbá Studies in a Changing World: A Festschrift in Honour of Olúgbóyèga Àlàbá".

You will receive copy of this published work as soon as the publication comes out.

Thank you for your interest in our publication.

Sincerely

Deji Medubi

Production Editor

08023322901

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Chapter

# FÍÌMÙ ÀGBÉLÉWÒ GẸ́GẸ́ BÍ OHUN-ÈLÒ ÌKỌ́NI NÍ ÀṢÀ ÀTI LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ: FÍÌMÙ ARUGBÁ ÀTI BAṢỌ̀RUN GÁÀ GẸ́GẸ́ BÍ ÀWÒTA

Adéyẹmí Abíọ́dún Adéyínká.
àti
Ìfẹ́olúwa Theophilus Akínṣọlá

*Àmúlò ohun-èlò ìkọ́ni ṣe pàtàkì nínú èlò-ìkọ́ni nítorí pé ó ń jẹ́ kí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ní ìtumọ̀ sí akẹ́kọ̀ọ́ kí ó sì yé wọn ju èyí tí olùkọ́ kò lò wọ́n. Wíwo fíìmù àgbéléwò Yorùbá àti ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àwọn àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn inú wọn jẹ́ ọ̀nà kan tí olùkọ́ lè gbà kọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn. Púpọ̀ nínú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ òde òní ni kò ní ìmọ̀ tí ó kún lórí àṣà àtii lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá nítorí kò sí ẹ̀kọ́ tí ó péye lórí àwọn kókó wọ̀nyí ní ilé-ẹ̀kọ́ bẹ́ẹ̀ ni púpọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ kò ka ìwé tí a kọ lórí àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá mọ́. Ìbéèrè lórí àṣà àti lítíréṣọ̀ jẹ́ kàn-ń-pá fún akẹ́kọ̀ọ́ láìmti dáhùn nínú ìdánwò àbájáde oníwèé mẹ́wàá. Méjì lára ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ fíìmù àgbéléwò Yorùbá tí bébà yìí yàn láàyò ni Arugbá àti Baṣọ̀run Gáà. Bébà yìí ṣe àgbéyẹ̀wò bí fíìmù àgbéléwò Yorùbá ṣe bẹ̀rẹ̀ àti àwọn àbùdá tí ó mú un jẹ́ ẹ̀ka lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ó tún ṣe àgbéyẹ̀wò ohun-èlò, àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn nínú àwọn fíìmù tí a yàn láàyò yìí. Síwájú sí i, bébà yìí ṣe àlàyé bí olùkọ́ ṣe lè fi fíìmù yìí kọ́ akẹ́kọ̀ ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Àgbékalẹ̀ bébà yìí ni ó wáyé nípa ṣíṣe àmúlò tíọ́rì méjì tí ó bá iṣẹ́ yìí mu-ìfàkíyèsí-nímọ̀ àti ìfojú-àṣà-wò ó sì gúnlẹ̀ nípa ṣíṣe àfikún ìmọ̀ pé ojú ọ̀pọ̀ olùkọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá yóò ṣí sí ọ̀nà yìí láti kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.*

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**ÌFÁÁRÀ**

Fífi fíìmù àgbéléwò Yorùbá yanjú ìṣòro tí ó ń kojú kíkọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni iṣẹ́ ìwádìí yìí dá lé. Ní ṣíṣe èyí, a óò máa ṣe àgbéyẹ̀wò bí a ṣe lè lo àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni pàtàkì fún kíkọ́ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, pàápàá jùlọ ní ilé-ẹ̀kọ́ girama. Fíìmù Arugbá àti Baṣọ̀run Gáà ni a yàn gẹ́gẹ́ bí àwòta iṣẹ́ yìí. A yan fíìmù méjéèjì láàyò fún ìwádìí yìí nítorí pé a ṣe àkíyèsí pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹ̀lẹ̀ nínú àwọn fíìmù náà ṣeé lò bí àpẹẹrẹ láti ṣàlàyé àwọn orí-ọ̀rọ̀ ajẹmáṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tó wà nínú kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù Yorùbá fún ilé-ẹ̀kọ́ girama. Nínú àwọn fíìmù méjéèjì yìí náà ni a óò sì ti ṣe àfàyọ àwọn àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tó jẹ yọ, tí ó sì bá àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmáṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn inú kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù ilé-ẹ̀kọ́ girama mu.

Èyí já sí pé a óò ṣe àyẹ̀wò bí àwọn àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tó jeyọ nínú àwọn fíìmù náà ṣe jẹ mọ́ ètò ìkọ́ni ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ní ilé-ẹ̀kọ́ girama. Nítorí ìdí èyí a kò ní ṣàìsọ̀rọ̀ ṣókíṣókí lórí iṣẹ́ àwọn aṣáájú lórí àṣà Yorùbá, lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, fíìmù àgbéléwò Yorùbá àti kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù nínú ètò ìkọ́ní, gẹ́gẹ́ bí ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá nínú kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù ilé-ẹ̀kọ́ girama. Èrèdí iṣẹ́ ìwádìí yìí ni láti mú kí ètò ìkọ́ni ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá rọrùn fún olùkọ́, kí ẹ̀kọ́ nípa àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá sì yé akẹ́kọ̀ọ́ yékéyéké, nípasẹ̀ gbígbé fíìmù àgbéléwò Yorùbá kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni pàtàkì fún kíkọ́ ẹ̀ka ẹ̀kọ́ náà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ló ti wà nílẹ̀ lórí ọ̀nà tí a lè gbà kọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ní ilé-ẹ̀kọ́ girama àti pé kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù Yorùbá fún ilé-ẹ̀kọ́ máa ń dábàá ohun-èlò ìkọ́ni fún kókó-ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan, a ṣe àkíyèsí pé kò tíì fi bẹ́ẹ̀ sí iṣẹ́ ìwádìí tí ó ṣe àgbékalẹ̀ àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ohùn-èlò ìkọ́ni ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn. Bí a bá sì fi ojú lámèyítọ́ wo àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá dáadáa, a ó ri pé ṣe ni àwọn òǹkọ̀tàn fíìmù náà máa ń mọ̀-ọ́n-mọ̀ ṣe àfihàn àwọn nǹkan ìbílẹ̀ Yorùbá láti ṣe ìgbéláruge fún wọn àti láti dá àwùjọ lẹ́kọ̀ọ́. Gẹ́gẹ́ bí yóò ti ṣe fojú hàn nínú àwọn fíìmù méjéèjì tí a fi ṣe àwòta iṣẹ́ yìí, a lè sọ pé ilé ìṣúra ọgbọ́n, èrò, ìṣe, ẹ̀sìn, ìṣẹ̀se àti ohùn-ẹnu Yorùbá ni àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá jẹ́.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## TÍỌRÌ ÀMÚLÒ FÚN IṢẸ́ YÌÍ

Tíọrì méjì tí ó jẹ́ ọ̀pákùtẹ́lẹ̀ fún iṣẹ́ yìí ni tíọrì Ìfàkíyèsínímọ̀ àti tíọrì Ìfojú-àṣà-wò.

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Adélékè àti Adébìyí (2003), àwọn tí ó jẹ́ abẹnugan tíọrì Ìfàkíyèsínímọ̀ (Inductive theory) ni Spinoza (1632) àti Bacon (1561). Wọ́n ṣàlàyé pé nígbà tí a bá fẹ́ ṣe ìwádìí pẹ̀lú tíọrì yìí, olùwádìí yóò ní àǹfààní láti wo ohun tó ń ṣe ìwádìí lé lórí, yóò sì le ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé lórí àwọn nǹkan kéékèèké tí ó rọ̀ mọ́ ìwádìí rẹ̀. Àwọn abẹnugan tíọrì Ìfàkíyèsínímọ̀ gbà pé ọpọlọ àti èrò ènìyàn kò ṣeé gbẹ́kẹ̀lé nítorí òjóró tí kò jìnnà sí ọmọ ènìyàn. Habib (2005) ṣàlàyé nípa tíọrì yìí nígbà tí ó wí pé:

> *In The New Organon, Bacon insisted that knowledge can arise only from actual obsevation of nature... The only secure way to arrive at knowledge, then is by a ''true induction'', whereby reason is applied to observed facts; only in this way can ideas and axioms be generated. (o.i 313)*
>
> *(Nínú ìwé rẹ̀ tí ó pè ní ''The New Organon'', Bacon tẹnu mọ́ ọn pé ìmọ̀ lè wáyé láti ara àkíyèsí ṣíṣe gan-an sàn-án... Ọ̀nà tí ó pamọ́ jùlọ láti ní ìmọ̀ ni fífa òye yọ láti inú àdáwò, níbi tí a ti ń ronú lórí ohun gbogbo tí a kíyèsí; nípa ọ̀nà yìí nìkan ni a lè gbà ní òye àti ìlànà. O.i 313)*

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìwádìí ìmọ̀ sáyẹ́nsì ni àwọn onímọ̀ tíọrì yìí gbé tíọrì náà kalẹ̀ fún, a ó lò ó fún àtúpalẹ̀ fíìmù àgbéléwò Yorùbá torí pé ṣíṣe náà ni a ó ṣe àkíyèsí àwọn ohun tí a ńlò nínú fíìmù náà lẹ́yìn tí a bá wò ó tán. Adélékè àti Adébìyí (2003) tilẹ̀ fi kún àlàyé wọn pé fún ìmọ̀ lítíréṣọ̀, ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu àti àṣà ilẹ̀ Yorùbá, ìfàkíyèsínímọ̀ ni olùwádìí gbọ́dọ̀ lò. Bóyá nítorí pé àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ yìí jẹ mọ́ àkíyèsí ṣíṣe ni wọ́n ṣe sọ bẹ́ẹ̀.

Nítorí pé àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ àṣà Yorùbá ni a fẹ́ fi àkíyèsí ní ìmọ̀ nípa wọn nínú àwọn fíìmù náà, a ó tún ṣe àmúlò tíọrì ìfojú-àṣà-wò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí. Abímbọ́lá (1982) tilẹ̀ fi yé wa pé kí á tó lè rí ìlànà lámèyítọ́ lítíréṣọ̀ tí ó pé, a níláti jẹ́ kí irú ìlànà bẹ́ẹ̀, bí ó ti wù kí ó jẹ́ ti òde-òní tó, ní ọwọ́ àṣà Yorùbá nínú. Àwọn agbátẹrù tíọrì ìfojú-àṣà-wò sọ pé iṣẹ́ tí lítíréṣọ̀ máa ń ṣe ni láti dáàbò bo àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ kan, nítorí náà ohun tí ó gbọ́dọ̀ jẹ lámèyítọ́ lógún ni ṣíṣe àfihàn irú àwọn àṣà tó súyọ nínú iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀. Akitiyan yìí

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

gẹ́lẹ́ ni a ó gbìyànjú láti ṣe nínú iṣẹ́ yìí nítorí pé a ó máa gùnlé tíọ̀rì ìfojú-àṣà-wò láti tọ́ka sí àwọn àṣà àti ohùn ẹnu Yorùbá tí ó máa ń súyọ nínú àwọn fíìmù tí a fi ṣe àwòta. Tíọ̀rì ìfojú-àṣà-wò dúró lórí bí àṣà ṣe wúlò fún àwùjọ, oríṣiríṣi ẹ̀ka ìmọ̀ ni a sì lè lò ó fún. Ọmọlọlá (2013) sọ pé àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ bí Fìlọ́sọ́fì, Sosíọ́lọ́jì, ìmọ̀ Àwùjọ-Àdáyébá (Anthropology), Mẹtafísíìsì, Ọrọ̀-ajé, Ọ̀ṣèlú àti Èdè ló ń lo tíọ̀rì yìí. Lewis (2012 ) náà jẹ́rìí sí ìlò tíọ̀rì yìí nínú oríṣiríṣi ẹ̀ka ìmọ̀.

Àwọn agbátẹrù tíọ̀rì yìí pín sí ọ̀nà méjì. Àwọn ìsọ̀rí kìn-ín-ní rí àṣà gẹ́ẹ́ bí ohun tí kò gbọdọ̀ yí padà nígbà tí àwọn ìsọ̀rí kejì rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí àyípadà máa ń dé bá tí ó sì gbọdọ̀ jẹ́ atáyéṣe. Ojú ìsọ̀rí méjèèjì yìí ni a fi wo àṣà nínú àwọn fíìmù wa. Gẹ́gẹ́ bí Edgar àti Sedgwick (2002:3) ṣe ṣàlàyé, tíọ̀rì ìfojú-àṣà-wó bẹ̀rẹ̀ láti orí onírúurú ìtumọ̀ tí oníkálukú ń fún àṣà. Èrò àwọn onímọ̀ yìí ni pé tíọ̀rì ìfojú-àṣà-wò pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ ṣùgbọ́n gbogbo ẹ̀ka rẹ̀ ni ó fara mọ́ àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun ìdánimọ̀ wọn. Edgar àti Sedgwick (2002) tún ṣe àlàyé pé ipa ìfojú-àṣà-wò ni pé àwọn détà tí a fẹ́ ṣíṣẹ́ lé lórí máa ń jẹ́ èròjà tàbí àwọn nǹkan pàtàkì tí à ń bá pàdé ní àwùjọ lápapọ̀.

Èyí fi hàn pé lílo tíọ̀rì ìfojú-àṣà-wò pẹ̀lú ìfàkíyèsí-nímọ̀ fún iṣẹ́ wa yìí yóò kógo já fún yíyẹ ìjẹyọ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn wò nínú àwọn fíìmù tí a fi ṣe àwòta. Tíọ̀rì ìfàkíyèsí-nímọ̀ ni a ó gbára lé jù lọ nígbà tí a bá ń wo bí àwọn àwọn àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn tó jẹ yọ nínú fíìmù ṣe bá kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù mu sí nínú iṣẹ́ yìí. Àmọ́ ṣá, àmúlùmọ́là tíọ̀rì méjèèjì ni a ó fi ṣe àfàyọ àwọn àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn nínú fíìmù tí a fi ṣe àwòta.

## FÍÌMÙ ÀGBÉLẸ́WÒ GẸ́GẸ́ BÍ Ẹ̀KA LÍTÍRÉṢỌ̀ YORÙBÁ

Àkíyèsí àwọn onímọ̀ ti fi hàn pé eré-oníṣe alohùn/àpilẹ̀ṣe onílànà Ògúnǹdé ni ó dàgbà sókè láti di fíìmù àgbéléwò Yorùbá. Ògúndèjì (1992:16) ṣàlàyé pé irúfẹ́ eré-oníṣe alohùn yìí nìkan ni ó ṣeé dákọ sínú ìwé nítorí pé ìhun rẹ̀ lápapọ̀ bá ti eré oníṣe ti àtọ̀húnrìnwá mu. Ògúndèjì(1992:42) nínú akitiyan rẹ̀ láti ṣàlàyé eré-oníṣe onílànà Ògúnǹdé tẹ́ pẹpẹ àwọn orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti lò fún irúfẹ́ eré-oníṣe yìí.

Àwọn orúkọ tí iṣẹ́ ìwádìí náà fi hàn ni; *"Folk opera(eré ìbílẹ̀ oníjó-lórin); Popular travelling theatre(tíátà mùtúmùwà alágbèéká); Modern travelling theatre(tíátà òde-òní alágbèéká); Contemporary travelling theatre(tíátà bágbàmu alágbèéká); Modern traditional theatre(tíátà tòde-òní mọ́ tàbáláyé) àti Professional Itinerant theatre(tíátà ajẹ mọ́ṣẹ́-àmúṣe alágbèéká).''* Lẹ́yìn tí

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ó tọ́ka sí àléébù àwọn orúkọ yìí ní ọ̀kọ̀ọ̀kan ní ó wá tẹ́ pẹpẹ orúkọ tó dá lábàá fún un nínú iṣẹ́ rẹ̀ ọdún 1987 àti 1988. Orúkọ náà sì nìyí: "*Ogunde dramatic tradition and movement (eré-oníṣe onílànà Ògúnǹdé àti àjọ òṣèré rẹ̀)"*.

Àlèébù tí orúkọ ti Ògúndèjì yìí ní ni pé orúkọ ẹnì kan ṣoṣo ni ó fi pè é nígbà tí ó jẹ́ pé ọ̀pọ̀ ni àwọn tó ti kópa nínú fífi ìlànà náà múlẹ̀. Àmọ́ ṣá, a gba àbá rẹ̀ yìí wọlé torí pé orúkọ tí ó lò fi ìyàtọ̀ hàn láàrin àwọn eré-oníṣe yìí àti àwọn yòókù. Ohun kan tó jẹ wá lógún jùlọ níbí ni ọ̀rọ̀ ìdàgbàsókè tó dé bá eré-oníṣe onílànà Ògúnǹdé títí tí ó fi di ohun tí a mọ̀ sí fíìmù àgbéléwò. Èyí ni yóò ràn wá lọ́wọ́ láti le fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ẹ̀yà lítíréṣọ̀ Yorùbá ni àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá jẹ́. Ògúndèjì (1992:51-54, 2014) tẹ́ pẹpẹ àwọn ìdàgbàsókè tó ti dé bá eré-oníṣe onílànà Ògúnǹdé láti ọdún 1944 tó ti bẹ̀rẹ̀ títí di lọ́ọ̀lọ́ọ̀ yìí. Ó ṣàlàyé pé eré-onítàn "*The Garden of Eden and the Throne of God*" ni ó fi bẹ̀rẹ̀ àti pé ọdún 1946 ni ó bẹ̀rẹ̀ sí ní gbé eré káàkiri. Ògúndèjì ṣàlàyé pé láàrin ọdún 1944 sí ọdún 1950 ni Ògúnǹdé tẹra mọ́ eré oníjó-lórin tí ó fara pẹ́ ti "native air opera'' àti "sacred Cantata'' nípa àmúlò orin. Ògúndèjì tẹ̀síwájú láti ṣàlàyé pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn eré rẹ̀ nígbà náà máa ń jẹ mọ́ ìtàn inú Bíbélì, Ògúnǹdé ta àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ yọ nípa ìṣàmúlò àṣà ìbílẹ̀ àti fọ́nrán eré-oníṣe eégún aláré fún ìgbà àkọ́kọ́.

Láàrin ọdún 1950 sí ọdún 1965 ni àwàdà ṣíṣe kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ sí í fara hàn kedere nínú eré-oníṣe onílànà Ògúnǹdé. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ògúndèjì, Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ ni ó tẹra mọ́ eré aláwàdà yìí ní ẹ̀yìnọ̀rẹyìn tí ó sọ ọ́ di ẹ̀ka kan ní ààyè ara tirẹ̀ nínú eré-oníṣe onílànà Ògúnǹdé. Ògúndèjì tún tọ́ka sí Ọlá Ọmọnìtàn (Ajímájàsán), Òjó Ládiípọ̀ (Bàbá Mèró) àti àwọn Jèkọ́ọ̀bù, Pápàlolò àti Adérùpọkọ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn eléré tí ó tún kópa nínú fífi ìdí eré aláwàdà yìí múlẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ògúndèjì, ọdún 1965 ni Ògúnǹdé bẹ̀rẹ̀ sí í wá àkọlé Yorùbá fún àwọn eré rẹ̀, *Yorùbá Ronú* ni ó sì fi bẹ̀rẹ̀ ìlànà tuntun yìí. Yàtọ̀ sí èyí, lẹ́yìn òmìnira yìí ni à lè sọ pé fíìmù àgbéléwò bẹ̀rẹ̀ sí ní dìdelẹ̀. Ògúndèjì sọ pé oríṣìríṣì ìdàgbàsókè tuntun lo tún ti jẹ yọ lóde-òní lára wọn ni eré ṣíṣe lórí rédíò, tẹlifíṣàn, sinimá àti àwo rẹ́kọ́ọ̀dù. Ògúndèjì fi yé wa pé ọdún 1976 ni sinimá bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu.

Ọmọlọlá (2013), nínú akitiyan rẹ̀ lórí fíìmù àgbéléwò Yorùbá náà gbà pé ṣíṣe eré ọlọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ láti ọwọ́ àwọn òṣèré bí Hubert Ògúnǹdé, Lérè Pàímọ́, Oyin Adéjọbí, Kọ́lá Ògúnmọ̀lá, Òjó Ládiípọ̀ (baba Mèró), Moses Adéjùmọ̀ (baba Sàlá), Adéyẹmí Afọláyan (Adélove), Ìṣọ̀lá Ògúnṣọlá (I-show-Pepper) àti àwọn òṣèré tíátà mùtúmùwà alágbèéká ni ó wọ́pọ̀ kí fíìmù ṣíṣe tó dé sí àwùjọ

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Yorùbá. Ó tilẹ̀ gbà pé a lè tọpinpin orirun fíìmù gbígbé jáde lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà sí ọ̀dọ̀ fíìmù Yorùbá, nítorí pé ìdàgbàsókè àwọn tíátà alágbèéká wọ̀nyí ni ó ṣí ojú Nàìjíríà sí fíìmù gbígbé jáde. Ó ní ọdún 1960 ni àwọn ẹgbẹ́ onítíátà alágbèéká kọ́kọ́ bá tẹlifísàn pàdé, tí wọ́n sì bá àwọn èròjà ìmọ̀ ẹ̀rọ "celluloid" àti ìrin-iṣẹ́ ìyafídíò pàdé ní ọdún 1980. Láti ìgbà yìí ni wọ́n ti bẹ̀rẹ̀ sí gbé eré wọn jáde pẹ̀lú fọ́nrán fídíò.

Adágbádá (2014) ṣe àfihàn rẹ̀ pé ìbẹ̀rẹ̀ ìpòórá fíìmù onílànà-sinimá lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà so mọ́ ìbẹ̀rẹ̀ lílo ẹ̀rọ fídíò fún yíya fíìmù. Àlàyé rẹ̀ yìí, gẹ́gẹ́ bí i ti Ọmọlọlá (2013) náà fi hàn pé àkókò tí a bẹ̀rẹ̀ sí í lo ẹ̀rọ fídíò yìí ni àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá bẹ̀rẹ̀. Haynes àti Okome (1997:50) náà fi yé pé nígbà tí ọdún 1980 yóò fi dópin, fíìmù àgbéléwò ti wà ní ojú ọpọ́n. Àwọn òṣèré ti bẹ̀rẹ̀ sí ní í gbé fíìmù àgbéléwò jáde. Fíìmù àkọ́kọ́ tí Haynes àti Okome (1997:50) sọ pé wọ́n gbé jáde ni *Ẹkún* tí Àlàdé Arómirẹ́ ṣe, lẹ́yìn èyí ni àwọn ilé-iṣẹ́ tẹlifíṣàn náà sì bẹ̀rẹ̀ sí gbé àwọn eré ọlọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ wọn jáde gẹ́gẹ́ bí fíìmù àgbéléwò tí wọ́n sì ń tà wọ́n síta. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ògúndẹ̀jì (2014:40) jẹ́ ká mọ̀ pé ẹnu àwọn onímọ̀ kò tíì kò lórí àkókò tí fíìmù àgbéléwò Yorùbá bẹ̀rẹ̀ ní pàtó, a ṣe àkíyèsí pé àríyànjiyàn àwọn onímọ̀ tí Ògúndẹ̀jì náà tẹ́ pẹpẹ wà láàrin ọdún 1988 sí ọdún 1991. Láàrin ọdún mẹ́ta yìí ni a gbà pé àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá bẹ̀rẹ̀.

Ní báyìí ó ṣòro láti mọ iye fíìmù agbéléwò Yorùbá tí ó ti jáde nítorí ìdàgbàsókè tí ó ti dé bá a. Haynes àti Okome (1997:50) tilẹ̀ tọpinpin ìgbéjáde fíìmù àgbéléwò Yorùbá. Ó sọ pé ní ọdún 1994 ni àwọn ilé-iṣẹ́ tó ń gbé fíìmù jáde fọwọ́ sí fíìmù mẹ́ta péré fún gbígbé jáde. Ọdún 1995 ni wọ́n fọwọ́ sí ọ̀kànlélógba, bẹ́ẹ̀ ni ní ọdún 1996 ni wọ́n fọwọ́ sí ọ̀tàlélúgba fíìmù fún gbígbé jáde ṣùgbọ́n àkíyèsí tiwa ni pé ọ̀kẹ́ àìmọye fíìmù àgbéléwò Yorùbá ló n jáde lọ́dún lẹ́nu lọ́ọ̀lọ́ọ̀ yìí, tí ilé-iṣẹ́ tó n gbé fíìmù jáde sì ń fọwọ́ sí i. Àmì ìdàgbàsókè ni a ṣe àkíyèsí pé èyí jẹ́. Láìfa ọ̀rọ̀ gùn ju bí ó ṣe yẹ lọ, àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá jẹ́ ẹ̀ka eré-oníṣe Yorùbá tí a lè fi sí abẹ́ eré-oníṣe onílànà-Ògúnndé-mọ́-tòde-òní, pàápàá jùlọ nítorí àwọn àbùdá ajẹmọ́ lítíréṣọ̀ tí wọ́n ní. Lára àwọn àbùdá náà ni pé; ó máa ń ní akópa, ẹ̀dá-ìtàn, òǹwòran, ibi ìṣèrẹ́, ìbùdó-ìtàn, kókó-ọ̀rọ̀, ọ̀pó-ìtàn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ; ó máa ń ṣe àfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ nítorí inú àwùjọ ni ó ti máa ń yan kókó-ọ̀rọ̀ rẹ̀; àwọn àṣà àti ìṣe àwùjọ máa ń hàn nínú rẹ̀; ó máa ń ṣe àmúlò ọnà-èdè tí í ṣe èdè lítíréṣọ̀; ó sì wà fún ìdárayá àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀.(Adébíyìí, 2012:55-64)

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## ÀWỌN ÀṢÀ YORÙBÁ

Àrẹ̀mú (2001:26) sọ pé àṣà ni ohun tí a mọ ènìyàn tàbí ẹ̀yà kan mọ̀ ṣùgbọ́n Adéyínká (n.d.) ní àṣà àti ìṣe ni gbogbo nǹkan tó ti di bárakú fún àwọn olùgbé àwùjọ kan bí ó ṣe jẹ mọ́ ọ̀rọ̀, èrò, àti ìṣe wọn. Fún ìdí èyí àṣà ni à bá máa pè ní lọ́rọ̀ , lérò àti níṣe.  Adéoyè (2003) náà ṣàlàyé pé àṣà jẹ mọ́ ìrírí, ìhùwàsí, ìgbésí-ayé, ìgbàgbọ́ àti ẹ̀sìn ẹ̀yà kan. Ó ní bí ènìyàn bá ti fi ọkàn sí àṣà ni àṣà máa ń di bárakú ẹni ní ṣíṣe àti àìṣe, tí yóò sì dàbí òfin tí a gbẹ́kẹ̀lé tí yóò máa tọ́ ènìyàn sọ́nà nínú ohun gbogbo. Àlàyé rẹ̀ ni pé àṣà a máa dàbí òògùn àjísà ní ìgbà míràn. Ohun tí a rí dìmú nínú àlàyé àwọn onímọ̀ yìí ni pé ohunkóhun tí ó bá máa jẹ́ àṣà fún ẹ̀yà kan gbọ́dọ̀ ti di bárakú wọn, àtipé àṣà máa ń yàtọ̀ láti agbègbè sí agbègbè tàbí ẹ̀yà sí ẹ̀yà. A jẹ́ pé àṣà jẹ́ mọ́ gbogbo ìgbésí-ayé àwọn ẹ̀yá kan.

Lára àwọn onímọ̀ tó ti ṣiṣẹ́ ìwádìí ìjìnlẹ̀ lórí àwọn àṣà Yorùbá ni Ògúnbọ̀wálé (1971), Dáramọ́lá àti Jéjé (1975), Adéoyè (1979) Adéoyè (2003). Adéoyè (2003:12) sọ pé èdè tí àwọn ẹ̀yà kan ń sọ, bí wọ́n ṣe ń jẹun, irú oúnjẹ tí wọ́n máa ń jẹ, bí wọ́n ṣe ń ṣe ètò ẹbí, ìgbéyàwó, ogún pínpín, ẹ̀sìn sínsìn, iṣẹ́ ọnà ìlú àti orin, ètò ìjọbá, ètò ogun jíjà, ètò ìkóra-ẹni-níjàánu, eré ìdárayá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni àwọn ohun tí a lè pè ní àkóónú àṣà.

Lọ́rọ̀ kan, àpapọ̀ àwọn àṣà Yorùbá tí ó jẹ́ yọ nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ yìí ni àṣà ìgbéyàwó, oyún níní àti ìtọ́jú oyún, ìsọmọlórúkọ, iṣẹ́ abínibí (àgbẹ̀, ọdẹ, akọ̀pẹ, aláró, alágbẹ̀dẹ, ahunṣọ,onílù, onídìrí, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ), ìranra-ẹni-lọ́wọ́, oge ṣíṣe, eré ìdárayа, ogun jíjà, ìsìnkú, ìkíni, ogún pínpín, ìwà ọmọlúàbí, owó yíyá àti gbèsè sísan, aṣọ wíwọ̀, oyè jíjẹ àti ètò ìṣèlú, èèwọ̀, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè àti àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá (bí  Ògún, Ṣàngó, Ọ̀rúnmìlà, Ọ̀ṣun, Ọya, Yemọja, Èṣù, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ), ọ̀ràn dídá àti ìjìyà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn tó jẹ́ àkóónú àṣà Yorùbá wọ̀nyí náà ni a lè bá pàdé gẹ́gẹ́ bí kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmáṣà nínú kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù Yorùbá fún ilé-ẹ̀kọ́ girama.

A kò le ṣe ẹ̀kàrìkà àwọn àṣà ilẹ̀ Yorùbá tán torí pé bí eṣú ni wọ́n ṣe pọ̀. Àkíyèsí tí a gbọ́dọ̀ ṣe níbí ni pé púpọ̀ àwọn àṣà yìí ni ó jẹ mọ́ ìbágbépọ̀, èyí fi hàn pé ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà kan tí ó mú ọ̀rọ̀ ìbáṣepọ̀ láwùjọ ní ọ̀kúnkúndùn púpọ̀.

## LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ

Èrò àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá bí Babalọlá (1966,1991), Owólabí, Olúnládé, Adéráńtí àti Ọlábímtán (1985)  àti Ilésanmí (1987) fi hàn pé àwùjọ Yorùbá ní irúfẹ̀ lítíréṣọ̀ kan tí ó máa ń wà ní ọpọlọ àwọn ọ̀mọ̀ràn. Babalọlá  (1959)

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ṣàlàyé pé lítíréṣọ̀ ni àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ ní èdè kan tàbí òmíràn. Ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ tí ó já sí ewì, àròsọ, ìtàn, àlọ́, ìyànjú, ìròhìn tàbí eré-onítàn, eré akọ́nilọ́gbọ́n lórí ìtàgé. Kò sì tó di àkọsílẹ̀ (ìyẹn ni pé kí á tó lè pè é ní lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ) a ti gbọ́dọ̀ tẹ̀ ẹ́ jáde nínú ìwé, lítíréṣọ̀ le wà nínú ọpọlọ àwọn ọmọ̀ràn . Babalọlá (1991) tún lítíréṣọ̀ Yorùbá fún ní ìtumọ̀. Ó pè é ní àkójọpọ̀ ohùn ẹnu tàbí ìjìnlẹ̀ èdè tí a gbé ka orí ìrírí, àkíyèsí àti ìgbé-ayé Yorùbá láti ìradíran. Èyí sì tún ń fi igbàgbọ́, àṣà, iṣẹ́ àti iṣe tàbí ihùwásí àwọn Yorùbá hàn.

Àwọn oríkì méjèèji tí ọ̀jọ̀gbọ́n Adébóyè Babalọlá fún lítíréṣọ̀ yìí kò yàtọ̀ sí ara wọn ní ìtumọ̀,bẹ́ẹ̀ ni kò sì tako èrò Owólabí, a.y. (1985), gẹ́gẹ́ bí Oyèrìndé àti Alimi (2011) ṣe fi hàn nínú iṣẹ́ wọn. Owólabí, Olúnládé, Adéránti àti Ọlábímtán (1985) ṣàlàyé pé ọgbọ́n àti ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí a ti kó jọ yálà gẹ́gẹ́ bí ìtàn, òwe tàbí ewì ni à ń pè ní lítíréṣọ̀. Wọ́n fi kún un pé àkójọpọ̀ yìí lè wà lágbárí, ó sì lè wà nínú ìwé. Ní yíyiri oríkì Owólabí àti àwọn yòókù rẹ̀ (1985) àti oríkì Babalọlá (1991) wò finnífinni, Oyèrìndé àti Alimi (2011) ṣàlàyé pé lítíréṣọ̀ Yorùbá ni:

> *Àkójọpọ̀ ìmọ̀, òye àti àkíyèsí tí ó dá lé orí ìgbé-ayé àwọn Yorùbá tí a fi ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó nó orísirísi àṣàyàn ẹ̀wà-èdè àti ètò tí ó gún régé gbé kalẹ̀.ó le jẹ́ nípa sísọ jáde lẹ́nu tàbí kíko sílẹ̀ bóyá ní ìlànà ọ̀rọ̀ geere tàbí ìlànà ewì.(o.i 2 )*

Àlàyé Ilésanmí (1987) lórí lítíréṣọ̀ Yorùbá, kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ti àwọn onímọ̀ yòókù:

> *Lítíréṣọ̀ ni ìlànà tí à ń gbà sọ fáyé gbọ́ ohun tó jẹ ni lọ́kàn nípa àyíká ẹni,tí a gbé kalẹ̀ lọ́nà àlùmọ̀kọ́rọ́yín lọ́pọ̀ ìgbà láì dárúkọ pàtó àwọn ẹni tí ọ̀rọ̀ kàn gan-an,ṣùgbọ́n tí àṣàyàn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ pẹ̀lú ohùn tó fẹwà fú ohun tí à ń sọ,máa ń ṣáábà jẹ ẹni tó ń ṣe àgbékalẹ̀ náà lógún.(o.i 17)*

Àlàyé finnífinni lórí ohun tí lítíréṣọ̀ jẹ́ láwùjọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àwọn aṣáájú ṣe fi hàn, jẹ́ kó di mímọ̀ pé a lè fi ohùn ẹnu wa gbé irúfẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá kan jáde. Irúfẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá yìí ni a mọ̀ sí lítíréṣọ̀ alohùn. Ó jẹ́ ẹ̀yà lítíréṣọ̀ Yorùbá tí a máa ń fi ohùn gbé jáde. Ohun tí à ń pè ní lítíréṣọ̀ alohùn yìí ni a ti fi ìgbà kan mọ̀ sí lítíréṣọ̀ àbáláyé tàbí lítíréṣọ̀ àtẹnudẹ́nu. A lè wo orúkọ yìí (lítíréṣọ̀ alohùn) gẹ́gẹ́ bí ìdàgbàsókè tí ó ń dé bá èdè. Orímóògùnjẹ́ (1996) pe lítíréṣọ̀ alohùn yìí ní:

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

> Ilé iṣura ọgbọ́n, èrò, ìgbàgbọ́, iṣe, èdè àti ìhùwàsí àwọn ènìyàn kan. Gbogbo bí ẹ̀yà kan ṣe rí ni ó máa ń hàn nínú lítíréṣọ̀ wọn.(o.i 2)

Nínú àlàyé Ikúdáyìsí (1992:77), ó hàn pé ''lítíréṣọ̀ alohùn (tí òún pè ní àtẹnudẹ́nu) jẹ́ àjogúnbá. Ìdí tó fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé wọ́n ti wà láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ tàbí láti ọdún gbọ́nhan. Adéjùmọ̀ (2009) náà dá sí ọ̀rọ̀ ohun tí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ́. Àlàyé tí ó ṣe ni pé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ́ ohun tó wà láàyè tí ó sì ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àpilẹ̀kọ. Lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ iṣẹ́ ọnà tí a fi ọ̀rọ̀ ẹnu gbé jáde. Ó jẹ́ àjogúnbá àwọn ọ̀rọ̀ àtinúdá, ìtàn, ìgbàgbọ́ àti àwọn orin àwùjọ wa láti ìgbà pípẹ́, tí ó sì n ti ẹnu iran kan bọ́ sí òmíràn. Ó tún ní àkóónú àlọ́, ìfọ̀rọ̀dárà, ọ̀rọ̀-akọ́nilẹ́nu, òwe, àrángbọ́, ọfọ̀, orin àti ìtàn lóríṣiríṣi, lọ́rọ̀ kan ó dúró fún ìtàn tí a fi ọ̀rọ̀ ẹnu gbé kalẹ̀. Lọ́pọ̀ ìgbà, akéwì alohùn Yorùbá máa ń ṣẹ̀dá ìṣèré rẹ̀ tí ó sì máa ń gbé e jáde pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ẹnu, ó sì máa ń fojú rinjú pẹ̀lú àwọn òǹwòran rẹ̀.

Gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àwọn onímọ̀ bí i Ògúndèjì (1991), Oyèrìndé àti Alímì (2011) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ṣe fi hàn, lítíréṣọ̀ gbogbo èdè àgbáyé ni ó ní ẹ̀ka mẹ́ta tí ó jẹ́ kárí-ayé. Ẹ̀ka mẹ́ta tó jẹ́ kárí-ayé tí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá pín sí ni **Ewì, Eré-oníṣe àti Ọ̀rọ̀ Geere**. Ògúndèjì (1991) ti ṣe akitiyan láti ṣe ìtúnpínsísọ̀rí àwọn ẹ̀ka mẹ́ta yìí bẹ́ẹ̀ ni Adú (2012) kín in lẹ́yìn. Ewì Alohùn ni ó tún pín sí ***Àrángbọ́*** (**kíkún**- ọfọ̀,oríkì àti ẹsẹ̀-ifá àti **kékeré**-òwe, àrọ̀ àti àlọ́ àpamọ̀), ***Ìsàré*** (**ajẹmẹ́sìn**- ìjálá, ẹ̀sà pípè, ìyẹrẹ̀-ifá, òrìṣà pípè àti **ajẹmáyẹyẹ**- rárà àti ẹkún ìyàwó(Ọ̀yọ́), ègè àti ìgbálá (Ẹ̀gbá), ọ̀sàré, àsíkò àti àdàn (Ifẹ̀), Olele (Ìjẹ̀ṣà), àṣamọ̀ (Èkìtì) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.) àti ***Orin*** (orin ọmọdé, orin ọdún ìbílẹ̀, orin àlùjó àti orin òwe). Eré-oníṣe ni ó pín sí **Ọdún Ìbílẹ̀** àti **Eégún Aláré**, nígbà tí ó pín Ọ̀rọ̀ geere Alohùn sí **Àlọ́ onítàn**, **Ìtàn ìwáṣẹ̀** àti **Ìtàn Akọnikàyéèfì**. Àwọn tó jẹ́ àkóónú ìpínsísọ̀rí iṣẹ́ Ògúndèjì yìí náà ló jẹ yọ gẹ́gẹ́ bí àkóónú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ alohùn tí a bá pàdé nínú kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù Yorùbá fún ilé-ẹ̀kọ́ girama.

## OHUN-ÈLÒ ÌKỌ́NI ÀTI PÀTÀKÌ RẸ̀ NÍNÚ ÈTÒ Ẹ̀KỌ́

Àkànlé (1992) pe àwọn ohun-èlò ìkọ́ni ní ''ohun-èlò amúṣẹ́yá.'' Àlàyé rẹ̀ lórí ohun tí ohun-èlò ìkọ́ni jẹ́ àti pàtàkì rẹ̀ nínú ètò ìkọ́ni ni a óò sì gbé yẹ̀wò ní àgbọn yìí. Onímọ̀ yìí fi yé wa pé ohun-èlò amúṣẹ́yá ṣe pàtàkì púpọ̀ fún olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá. Bí ohun èlò amúṣẹ́yá ṣe jẹ́ amúṣẹ́yá fún olùkọ́ náà ló jẹ́ amúṣẹ́yá fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ó máa ń jẹ́ kí ẹ̀kọ́ tètè yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láìlàágùn púpọ̀, ó sì tún máa ń dín wàhálà olùkọ́ kù nítorí pé púpọ̀ ohun tí olùkọ́ ìbá máa

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ṣe wàhálà láti jẹ́ kí ó yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ni ohun-èlò amúṣẹ́yá á ti ṣe àlàyé fún ra rẹ̀. Èyí kò le ṣàì máà rí bẹ́ẹ̀ nígbà tí ó jẹ́ pé ohun tí àwọn bá fi ojú rí máa ń pẹ́ lọ́kàn wọn ju ohun tí wọ́n kàn gbọ́ lásán tí wọn kò rí. Ohun-èlò ìkọ́ní tún máa ń jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ronú jinlẹ̀ dáadáa lórí kókó ẹ̀kọ́ tí olùkọ́ ń kọ́ wọn àti láti jẹ́ kí ìmọ̀ tí wọ́n rí gbà pẹ́ lórí wọn. Èyí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé nǹkan tí ènìyàn bá rí , tí ó fọwọ́ kàn, tàbí tí ó lò láti ṣe ohun kan máa ń pẹ́ nínú ọpọlọ ènìyàn. Ó sì tún ń jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ kópa nínú ètò ìkọ́ni, nígbà tí wọ́n bá ń dárúkọ tàbí fọwọ́ kan ohun-èlò tí olùkọ́ ń lò gẹ́gẹ́ bí amúṣẹ́yá.

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ni àwọn ohun-èlò wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí àlàyé Àkànlé (1992), wọ́n sì pọ̀ lọ súá bí ọlá Ọlọ́run ni. A máa ń lo ohun-elò ìkọ́ni bí *ohun-èlò àtọwọ́dá*. Wọ́n jẹ́ ohun-èlò ìkọ́ni tí a wá tàbí tí a pilẹ̀ ṣe fún ara wa fún ètò ìkọ́ni. Díẹ̀ lára àwọn ohun-èlò àtọwọ́dá ni ìwọ̀nyí: Pátákó ìfàlọ́wọ́, Pátákó ẹ̀gbẹ́ ògiri, ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì àti ẹ̀rọ móhùnmáwòrán àti ojú pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́.

Àkànlé (1992) tún sọ pé àwọn ohun-èlò mìíràn tí a lè lò ni nǹkan gan-an tí a fẹ́ kọ́. Eléyìí fẹ́ẹ̀ wúlò fún àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá nítorí gbogbo nǹkan tí a fẹ́ kọ́ ni ó wà ní àyíká wa tàbí ní agbègbè wa. Fi nǹkan gan-an tí o fẹ́ kọ́ síwájú wọn, bí ọpọ́n ifá, ọpọ́n ayò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, fi han àwọn akẹ́kọ́ kí wọ́n le rí i dáadáa, kí wọ́n fi ọwọ́ kàn án kí wọ́n sì lò ó.

Àkànlé (1992) tẹ̀ síwájú nípa ṣíṣe àlàyé pé bí a kò bá le mú nǹkan tí a fẹ́ kọ́ wá, a lè mú nǹkan mìíràn tí ó dàbí nǹkan tí a fẹ́ kọ́ (model) wá fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti rí. Nípa báyìí, wọn yóò le ní òye bí nǹkan náà ti rí. Ó ní nígbà mìíràn, ìwé kíkà àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà lè dúró gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò amúṣẹ́yá, pàápàá bí ìwé náà bá jẹ́ èyí tí àwòrán pọ̀ nínú rẹ̀. Kò ṣàì tún tọ́ka sí i pé ilé/ṣọ́ọ̀bù ìkọ́ni ní èdè, ìwé àtìgbàdégbà, ìmọ̀ àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n (abẹ́nà ìmọ̀) àti ìbẹ̀wò sí ibi pàtàkì fún ìmọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ náà jẹ́ ohun-èlò amúṣẹ́yéni pàtàkì. Àmọ́ ṣá, àlàyé onímọ̀ yìí kò dé orí pé a lè fi fíìmù àgbéléwò kọ́ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ìwádìí wa yìí yóò ṣe fi hàn.

## ÀṢÀ ÀTI LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ NÍNÚ FÍÌMÙ ARÚGBÁ

Bí a bá wo fíìmù àgbéléwò Arugbá ní àwòfín, a ṣe àkíyèsí pé àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí ó wúlò fún ìkọ́ni nílé-ẹ̀kọ́ girama pọ̀ nínú rẹ̀. Díẹ̀ lára àṣà Yorùbá tí ó jẹ yọ ni ẹ̀sìn ìbílẹ̀, ọdún ìbílẹ̀, ètò ìṣèlú, ìfibáléyangàn, aṣọ wíwọ̀, ìtọ́jú ọmọdé àti aboyún, ìkíni, orúkọ jíjẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ó ṣe àlàyé ẹ̀sìn ìbílẹ̀ àti ọdún ìbílẹ̀ tórí òun ló fojú hàn jù lọ, a tilẹ̀ le sọ pé ẹ̀sìn ìbílẹ̀ àti ọdún ìbílẹ̀ ni olú kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmáṣà tí a lè fi fíìmù náà kọ́. Àwọn àṣà yìí gan-an ni òǹkọ̀tàn fi

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

fíìmù náa fọn rere, torí pé ìgbésí ayé àwọnYorùbá ló jẹ yọ nínú fíìmù náà ló jẹ́ ká bá irúfẹ̀ àwọn àṣà mìíràn pàdé.

**Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀**: Bíbọ òrìṣà tí ó jẹ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá jẹ yọ nínú fíìmù Arugbá. A tilẹ̀ le sọ pé oríṣi ìbọ Yorùbá kan ni ó jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ ìtàn inú fíìmù náà. Òrìṣà odò tí a mọ̀ sí Yemọja ni fíìmù náà ṣe àfihàn bíbọ rẹ̀. A rí bí wọ́n ṣe máa ń yan Arugbá tí yóò rugbá òrìṣà yìí lọ sí odò, nípasẹ̀ bíbèèrè lọ́wọ́ ifá. Ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú ifá tí ó jẹ yọ nínú fíìmù náà túbọ̀ fi ìdí ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá múlẹ̀ nínú fíìmù náà. Àwọn Yorùbá máa ń bèèrè ohunkóhun tí wọ́n bá fẹ́ ṣe lọ́wọ́ ifá kí wọ́n tó ṣe é. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni wọ́n ṣe nínú fíìmù náà. Kí wọ́n tó yan ẹni tí ó máa rugbá tàbí kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ ọdún rárá, wọ́n gbọ́dọ̀ bèèrè lọ́wọ́ ifá kí wọ́n lè mọ bí ìrìnàjò yóò ṣe rí. Yàtọ̀ sí èyí, ìrúbọ jẹ́ àbùdá pàtàkì tí ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá ní, èyí sì jẹ yọ dáadáa nínú fíìmù náà. Ní ìparí fíìmù náà, wọ́n bọ Yemọja. Àwọn ohun tí ẹnu ń jẹ lóríṣiríṣi ni wọ́n kó sínú igbá ńlá kan tí abọrẹ̀ sì ń fọ́n ọn sójú omi tí wọ́n ń bọ. Bí wọ́n ti ń ṣe èyí ni wọ́n ń wúre lóriṣiríṣi, tí wọ́n sì ń bèèrè ohun tí wọ́n fẹ́ lọ́wọ́ òrìṣà odò. Àbùdá mìíràn tí ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá tún ní gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú fíìmù náà ni pé ó jẹ́ mímọ́. Ìwà àti ìṣe àwọn ẹlẹ́sìn náà tí ó jẹ́ mímọ́, ohun-èlò funfun funfun tí wọ́n máa ń lò àti ọ̀rọ̀ àrugbá tí kò gbọdọ̀ tíì mọ ọkùnrin ṣe àfihàn pé ẹ̀sìn náà jẹ́ mímọ́. Gbogbo

**Ọdún Ìbílẹ̀:** Ẹ̀sìn ìbílẹ̀ ni ó sábà máa ń bí ọdún ìbílẹ̀ nítorí pé gbogbo ẹ̀sìn ni ó ní àsìkò àjọ̀dún tirẹ̀. Ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń yàtọ̀ láti ìlú sí ìlú ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìdí ni pé òrìṣà/ìbọ tó gbajúgbajà ní ìlú/ẹ̀yà kan máa ń yàtọ̀ sí ti òmíràn. Ọdún ọ̀ṣun Ọ̀ṣogbo ni ó jẹ yọ nínú fíìmù yìí. A sì lè sọ pé gbogbo ìlànà tí wọ́n ń gbà ṣe ọdún ọ̀hún ni fíìmù náà ṣe àfihàn. Lásìkò ọdún ìbílẹ̀ náà gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú fíìmù yìí, dídá ifá ọdún; orin; ìlù; ijó; idán pípa; ìrúbọ; ìwúre; jíjẹ-mímu àti àríyá lóríṣiríṣi kò lè má jẹ yọ. Nínú fíìmù náà, lẹ́yìn tí wọ́n dáfá ọdún tán, wọ́n mú Arugbá lọ sọ́dọ̀ ọba kí ó le wúre fún un. Ààrẹ oníkòyí tún bá gbogbo ìlú sọ̀rọ̀ ní ojú agbo àríyá, lẹ́yìn èyí ni àwọn ènìyàn ìlú tàkòtó ijó lọ sí odò láti rúbọ sí Yemọja. A sì tún rí àwọn eégún náà tí wọ́n ń pitú ọwọ́ wọn láti dá àwọn ènìyàn láraya.

Yàtọ̀ sí àwọn àṣà Yorùbá tí a sọ pé ó jẹ yọ yìí, àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́-lítíréṣọ̀ alohùn náà jẹ yọ nínú fíìmù náà. Àwọn lítíréṣọ̀ alohùn tí a ṣe àkíyèsí jẹ́ àpẹẹrẹ ewì alohùn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a lè ka ọdún ìbílẹ̀ náà sí lítíréṣọ̀ alohùn torí ó jẹ́ ẹ̀ka kan lábẹ́ eré-oníṣe ìbílẹ̀. Àwọn lítíréṣọ̀ alohùn tí a kíyèsí pé ó jẹ yọ nínú

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

fíìmù Arugbá ni ìsàré (ìjálá, ẹ̀sà àti iyẹ̀rẹ̀-ifá), orin, eégún aláré , eré oníjó-lórin, àpárá, oríkì àti òwe. A ó sọ̀rọ̀ lórí ìjẹ yọ orin àti ẹ̀sà gẹ́gẹ́ bí olú kókó-ọ̀rọ̀ ajẹ mọ́-lítíréṣọ̀ alohùn tí ó jẹ yọ.

**Orin Ìbílẹ̀:** Láti ìbẹ̀rẹ̀ dé ìparí fíìmù náà ni orin ti kó ipa pàtàkì. Púpọ̀ àwọn orin tó jẹ yọ jẹ́ èyí tí wọ́n fi ṣe àpọ́nlé òrìṣà odò. Bí àpẹẹrẹ;

*Ọ̀ṣun lé tente ò e*
*Ọ̀ṣun lé tente o à*
*Ìyá àwa dòṣùpá o*
*Ọ̀ṣun lé tente*

*Ìyá nìyá àwa*
*Ìyá nìyá àwa*
*Idẹ ń bẹ lọ́wọ́*
*Idẹ ń bẹ lọ́wọ́...*

Bákan náà ni Oníkòyí kọ orin ìbílẹ̀ kan tí ó jẹ mọ́ ìtọ̀jú ọmọ tàbí fífún ọmọ ní ẹ̀kọ́ ilé. Orin náà nìyí;

*Ẹ bá wa tọ́jú ọmọ*
*Ẹ bá wa tọ́jú ọmọ*
*Àwa ò pé ẹ má yan àlè mọ́ o*
*Ẹ bá wa tọ́jú ọmọ*

**Ẹ̀sà Pípè:** Bákan náà ni a tún ṣe àbápàdé ohùn ẹ̀sà pípè tí ó jẹ́ oríṣi ìsàré kan. Ohùn ẹ̀sà ni Àyìnlá, oníbàtá Mákindé fi sọ ìtàn Ṣàngó àti onílù rẹ̀ nígbà tí Mákinwá ń gbáradì fún eré ori-ìtàgé rẹ̀. Ìwọ́hùn àti ìwéhùn ìsàré náà tí ó fi mọ́ àkóónú rẹ̀ bí ìtàn, oríkì,ìwéréǹde àti lílu ìlù bàtá sí i fi hàn pé ẹ̀sà pípè ni. Bí ó ṣe bẹ̀rẹ̀ nìyí;

*Olúgbọ́n ẹ jíire bí oo?*
*Ìrẹ̀sà àjẹ́jẹ́ tojú tìlalọ̀*
*Wọ́n ooooo*
*Wọ́n jíire jù bẹ́ẹ̀ lọ*
*Ìyá olúgbọ́n*
*Olúgbọ́n wọn kò gbọ́dọ̀ mawo*
*Àjẹ̀jẹ́ wọn kò gbọ́dọ̀ ṣorò*
*Esè kan ọlá, ẹsẹ̀ kan ọlà*

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

*A dífá fún Ṣàngó òun bàtá*
*N lọ rè é dá ọ̀ré*
*Ṣàátẹ́ ni orúkọ oníbàtá Ṣàngó ò...*

Yàtọ̀ sí èyí, ẹ̀sà tún jẹ yọ nínú eré oníjó-lórin tí ẹgbẹ́ òṣèrè Mákinwá ṣe, ó fi ẹ̀sà náà ṣe ìwéréǹde bí àwọn apẹ̀sà ṣe máa ń se tí wọ́n sì máa ń fi ẹ̀sà wọn síṣọ lójú ìwà ìbàjé àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Ó wí pé:

*Éééééé eee èèè éé*
*Gbogbo ẹ̀yin olórílẹ̀-èdè yìí*
*Tẹ́ ẹ rò pé ẹ gbọ́n nílé-ayé*
*Ayé ń polúkúrúmusu ú lọ*
*Ẹ̀ ń lọ*
*Ọ̀run ń polúkúrúmusu ú lọ*
*Ẹ̀ ń lọ...*

Yàtọ̀ sí àwọn wọ̀nyí, a tún ń gbọ́ ohùn ẹ̀sà àwọn eégún ní abẹ́lẹ̀ níbi ayẹyẹ ọdún ìbílẹ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohùn wọn ò jákè.

## ÀṢÀ ÀTI LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ NÍNÚ FÍÌMÙ BAṢỌ̀RUN GÁÀ

Nígbà tí a wo fíìmù Baṣọ̀run Gáà ní àwòfin, a ṣe àkíyèsí pé àwọn àṣà Yorùbá jẹ yọ nínú rẹ̀. Nínú fíìmù náà ni a ti ṣe alábàápàdé àwọn àṣà Yorùbá bí ètò ìṣèlú/ìṣèjọba, oyè jíjẹ/ìwúyè, ọ̀ràn dídá àti ìjìyà, ìkíni, ìpolówó ọjà, ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá, èèwọ̀, ìwà ọmọlúàbí, oògùn/ètùtù ṣíṣe, aṣọ wíwọ̀, ìfọmọlọ́kọ, ìtọ́jú ara ẹni, eré ìdárayá (ayò títa), orúkọ jíjẹ́, ogun jíjà, iṣẹ́ àgbẹ̀ àti ìlù lílù. Ẹ jẹ́ ká yẹ ìjẹ yọ ètò ìṣèlú/ìṣèjọba àti oyè jíjẹ/ìwúyè wò torí a lè sọ pé àwọn ni olú kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmáṣà tí fíìmù náà ṣe àfihàn tí a sì lè kọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ girama.

**Ètò Ìṣèlú/Ìṣèjọba:** Fíìmù Baṣọ̀run Gáà ṣe àfihàn ètò ìjèjọba ilẹ̀ Yorùbá níbi tí ọbá ti jẹ́ olórí tí ó sì tún ní àwọn ìjòyè tí wọ́n ń ràn án lọ́wọ́ nínú iṣẹ́ ìlú. Ètò ìṣèlú Ọ̀yọ́ tí ìtàn inú fíìmù Baṣọ̀run Gáà ti ṣẹlẹ̀ ni òǹkọ̀tàn tẹ́ pẹpẹ sínú fíìmù náà. Nínú ètò náà, ọba tí a mọ̀ sí "Aláàfin" ni aláṣẹ, ohun tí ó bá wí ni abẹ gé. Àmọ́ ṣá, Aláàfin kì í ṣe ''apàṣẹ-wàá,'' ìgbìmọ̀ Ọ̀yọ́mèsì tí í ṣe àwọn olóyè kábíyèsí le yẹ agbára rẹ̀ wò. Wọ́n jẹ́ ìgbìmọ̀ ẹlẹ́ni méje, lára wọn ni Baṣọ̀run (tí í ṣe olórí Ọ̀yọ́mèsì), Ṣàmù, Ọ̀tún, Osi, Kúdẹ̀ẹ̀fù, Alápinni àti Aṣípa. Àwọn ìjòyè wọ̀nyí ni afọbajẹ. Bí ọba bá sì ti ń ṣi agbára lò, wọ́n ní agbára láti ní kí ọbá ṣígbá wò. Bí àpẹẹrẹ, nígbà tí ọba Mọ́jèógbé lo agbára rẹ̀ lọ́nà àìtọ́ nípa

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

pípa Ìlọ̀rí onílù ní Jàbàtá (àna rẹ̀), nítorí pé ayaba kàn ń bá a jẹ̀wọ̀ lásán, àwọn Ọ̀yọ́mèsì pẹ̀lú àṣẹ Baṣọ̀run ránṣẹ́ sí ọba Májẹ̀ógbé pé kí òṣùpá rẹ̀ wọ̀ọ̀kùn l'Ọ́yọ̀ọ̀ nítorí pé gbogbo ìlú kọ̀ ọ́ ní ọba. Ìjòyè mìíràn tó tún ṣe pàtàkì nínú ètò ìṣèlú Ọ̀yọ́ ni Ààrẹ-Ọ̀nà-Kakaǹfò. Oyè ogun sì ni oyè yìí, bẹ́ẹ̀ sì ni olóyè yìí kò gbọdọ̀ gbé nínú Ọ̀yọ́ pẹ̀lú Aláàfin, ẹ̀yìn odi ìlú ni ó máa ń gbé. Ọyálàbí ni orúkọ Ààrẹ-Ọ̀nà-Kakaǹfò nínú fíìmù náà, òun sì ni Aláàfin Abíọ́dún tọ̀ lọ fún ìrànwọ́ nígbà tí Gáà pa á ní ọmọ, torí pé òun ni aṣáájú ogun Ọ̀yọ́.

**Oyè Jíjẹ/Ìwúyè:** Ètò ìwúyè ní ilẹ̀ Yorùbá tún jẹ́ àṣà Yorùbá mìíràn tí a kíyèsi pé ó jẹ yọ nínú fíìmù Baṣọ̀run Gáà. Ètò ìwúyè ọba Abíọ́dún Adégoólú sì ni òǹkọ̀tàn fi tẹ́ pẹpẹ àṣà yìí. Lẹ́yìn tí àwọn ọ̀yọ́mèsì ti yan Abíọ́dún gẹ́gẹ́ bí ẹni tí wọ́n fẹ́ fi joyè ni wọ́n ṣètò àti sọ fún un. Láti ibi tí àwọn ìjòyè ti ká a mọ́ ìdí ayò tí gbogbo wọ́n sì ké kábíyèsí lórí ìdọ̀bálẹ̀ wọn, lẹ́yìn tí wọ́n fi ipá mú un dọ̀bálẹ̀ tán (fún ìgbà ìkẹyìn), kó tó di pé ó sá lọ gan-an ni ìwúyè ti bẹ̀rẹ̀ sí ní í fojú hàn dáadáa. Lẹ́yìn èyí ni wọ́n mú un wọ ìpèbí (tí wọ́n pè ní ilé ọgbọ́n) lọ, tí Iba Ológbò sì rọ ọ́ ní omi ọgbọ́n àti ìmọ̀ yó bámú bámú. Ayẹyẹ ni wọ́n fi kásẹ̀ gbogbo ètò náà nílẹ̀. Lọ́jọ́ ayẹyẹ ìwúyè náà, wọ́n ṣe ìwúre fún ọbá tuntun, àwọn ayaba fi orin dá kábíèsí àti àwọn ènìyàn lára yá, wọ́n jó, wọ́n yọ̀, àwọn ìjòyè ( bẹ̀rẹ̀ láti orí Baṣọ̀run) sì kóòpẹ̀ láti kí ọba tuntun.

Níti àwọn lítíréṣọ̀ alohùn tó jẹ yọ, ewì alohùn ni ó pọ̀ jù. Lára wọn ni Ṣàngó pípè, orin, rárà, oríkì, ìwúre, ọfọ̀ àti òwe. Nínú àwọn ewì alohùn wọ̀nyí kò sí èyí tí kò jẹ yọ dáadáa, ìjẹ yọ wọn sì bá ọ̀gangan ipò àmúlò wọn mu tí a sì le fi wọ́n ṣe àpẹẹrẹ nínú kíláàsì ìkọ́ni ní lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Ẹ jẹ́ ká wo bí wọ́n ṣe lo orin gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ.

**Orin:** Orin ìbílẹ̀ Yorùbá ni ó je yọ nínú fíìmù Baṣọ̀run Gáà. Wọ́n kọ orin Ṣàngó pípè tí ó jẹ yọ ní ìbẹ̀rẹ̀ fíìmù náà, ìlù bàtá tí í ṣe ti Ṣàngó ni wọ́n sì lù sí orin náà. Orin náà lọ báyìí pé;

*...Gbà mí o má jẹ n jìn sí kànga*
*Ẹni aní ní í gba ni*
*Ọba ògo gbà mí o má jẹ n jìn sí kànga*
*Ẹni a ní ní í gba ni*
*Ọkọ ọya gbà mí o má jẹ jìn sí kànga*
*Ẹni a ní ní í gba ni...*

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Bákan náà, orin yùngbà tí àwọn ayaba fi máa ń ṣàpọ́nlé aláàfin Ọ̀yọ́ jẹ yọ níbi ayẹyẹ ìwúyè aláàfin Abíọ́dún, igbá tìtí sì ni ìlù irúfẹ̀ orin yìí. Àwọn ayaba á jókòó sí orí ẹní sẹ́gbẹ̀ẹ́ igbá tí wọ́n ti dojú ẹ̀ dé, wọn á sì máa fi ọwọ́ wọn tí wọ́n ti fi òrùka kúsanrín sí lu igbá náà láti fún wọn ní ohùn tí wọ́n fẹ́. Wọn a sì tún máa fi igbá kékeré kan dé ojú ìyá odó kan. Gbogbo ìwọ̀nyí jẹ́ kí àgbékalẹ̀ irúfẹ̀ ewì alohùn yìí ní àbùdá eré oníṣe ìbílẹ̀. Orin tí wọ́n máa ń kọ nìyí;

*Adégoólú ọkọ ayaba*
*Oúnjẹ ló ń sàgbà dèwe o...*

*Ó jọ pó mọ̀ ọn jó*
*Adégoólú...*

*Adégoólú laré òní ó yẹ ò*
*Èrò yà wá wò ó o...*

*Bérin jẹ erin a pagbo ò*
*Bérin jẹ erin a pagbo*
*Bérin jẹ erin a pagbo ò*
*Bérin jẹ erin a pagbo*
*Adégoólú dìde ó fọba hàn*
*Bérin jẹ erin a pagbo...*

Orín tún jẹ yọ nínú rárà tí Láọ̀rẹ́ sun nílé Iba, bí ó á ti pohùn lọ sàà ni yóò sì ti orin bọ̀ ọ́ tí àwọn elégbè rẹ̀ náà sì ń gbè é ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá. Orin náà ni ó fi bẹ̀rẹ̀ rárà tí ó ń sun fún Ìdárayá Òbé àti Ọláyìíòtán nígbà tí wọ́n ń ti òde àìsùn kan bọ̀, bí ó sì ṣe ń dá a ni àwọn elégbè rẹ̀ ń gbè é. Orin tí wọ́n ń kọ láti fi ṣàpọ́nlé àwọn ọmọ Baṣọ̀run náà nìyí;

Ọláyìíòtán mọ̀mọ̀ dé ọmọ Baṣọ̀run
Ó mọ̀mọ̀ dé ọmọ Baṣọ̀run
Òbé mọ̀mọ̀ dé ọmọ Baṣọ̀run
Ó mọ̀mọ̀ dé ọmọ Baṣọ̀run

A ṣe àkíyèsi pé orin ìbílẹ̀ náà ni orin ìwẹ̀ tí Àgbọ̀nyín sọ pé kí Akínkúnmi rán òun létí nígbà tí Akínkúnmi wá a wálé tí ó sì bá a lórí ìwẹ̀. Bákan náà ni orin ogun jíjà tún jẹ yọ lẹ́yìn tí ọba ṣígun fún àarẹ tán, àwọn ọmọ ogun ń fò sókè sódò, wọ́n sì ń kọrin àti nígbà tí wọ́n ṣẹ́gun Gáà tán.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## ÌFI-FÌÌMÙ-KỌ́NI NÍ ÀṢÀ ÀTI LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN

Lẹ́yìn tí ó ti fojú hàn pé àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí a lè bá pàdé nínú ètò ìkọ́ni máa ń pọ̀ nínú àwọn fìímù àgbéléwò Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn láti inú àwọn fìímù méjèèjì tí a fi ṣe àpẹẹrẹ, ohun tí ó kàn ni kí a wo bí a ṣe le lo àwọn fìímù náà fún ìkọ́ni. Nígbà tí olùkọ́ bá fẹ́ ṣe àmúlò fìímù àgbéléwò gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni, ó ní àwọn ìlànà tàbí ìgbésẹ̀ kan tí ó gbọ́dọ̀ tẹ̀lé, kí ètò ìkọ́ni rẹ̀ lè yanjú. Gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe fi hàn, àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn ni a lè fi ọ̀nà ìfi-fìímù-kọ́ni kọ́. Bí a bá fẹ́ lo ìlànà ìkọ́ni yìí, a nílàti kọ́kọ́ mọ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmáṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn tí a fẹ́ kọ́ ní sáà kan, lẹ́yìn èyí ni a ó wá ṣe àwárí àwọn fìímù àgbéléwò Yorùbá tó ṣe àfihàn àwọn kókó-ọ̀rọ̀ wọ̀nyí. A ṣe akíyèsí pé ó lè má sí àyè àti máa fi fìímù hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìjókòó kọ̀ọ̀kan torí kì í sábà ju ogójì ìṣẹ́jú lọ. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, olùkọ ti gbọ́dọ̀ kọ àwọn àkọlé fìímù tó fẹ́ fi ṣe ìkọ́ni rẹ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní sáà tó ń bọ̀ láti ìparí sáà àkọ́kọ́, kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti lọ wo àwọn fìímù náà nínú ìsinmi wọn kí wọ́n sì kíyèsí ìjẹ yọ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ á ti kọ fún wọ́n kí wọ́n tó lọ fún ìsinmi. Bí wọ́n bá sì wọlé sáà tuntun tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ sì bẹ̀rẹ̀, kí olùkọ́ àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa ṣe ìjíròrò lórí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ náà ló kù pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti inú àwọn fìímù tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ á ti wò nínú ìsinmi wọn.

Bákan náà nígbà tí olùkọ́ bá ń lo fìímù gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni, a gbà wọ́n ní ìmọ̀ràn láti tẹ̀lé àwọn ìlànà àti ìgbésẹ̀ tí a ti là kalẹ̀ lókè fún lílo ọ̀nà ìfi-fìímù-kọ́ni. Bí olùkọ́ bá ti pinnu lórí fìímù tó fẹ́ lò gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni ní sáà kan, ó gbọ́dọ̀ jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀, kí ó sì máa fún wọ́n níṣẹ́ ṣe nínú àwọn fìímù náà. Ó tilẹ̀ le fi fìímù náà han àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nílé-ẹ̀kọ́, bí ààyè bá wà tí àwọn olùdarí ilé-ẹ̀kọ́ sì fọwọ́ sí i.

Yàtọ̀ sí ìgbà tí olùkọ́ bá fẹ́ lo fìímù gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni, a gbà wọ́n ní ìmọ̀ràn láti máa dígbà fi fìímù Yorùbá hàn ní ilé-ẹ̀kọ́ yálà nígbà tí wọ́n bá ń ṣe ọ̀sẹ̀ Yorùbá (fún àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tó ń ṣe é) , ayẹyẹ ìparí ọdún tàbí ayẹyẹ mìíràn ní ilé-ẹ̀kọ́. Irúfẹ̀ àwọn fìímù tí wọn ó fi hàn báyìí gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ó ṣe ìgbélárugẹ fún àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Nípa báyìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ á rí ohun kan tàbí òmíràn dì mú nípa àṣà àti ìṣe Yorùbá nínú àwọn fìímù náà, yálà wọ́n rí ìtọ́sọ́nà gbà láti ọ̀dọ̀ olùkọ́ tàbí wọn ò ri gbà.

## ÀGBÁLỌGBÁBỌ̀

Nítorí pé iṣẹ́ ìwádìí yìí ti fi hàn pé a lè lo fìímù àgbéléwò gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, àwá gbà pé fífi fìímù kọ́ni jẹ́ ọ̀nà ìkọ́ni

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

pàtàkì tí ó lè dúró gẹ́gẹ́ bí olùrànlọ́wọ́ fún olùkọ́ nínú ètò ìkọ́ni rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò sí ohun tí a fi le dípò ipa olùkọ́ nínú kíláàsì, ìlò fíìmù àgbéléwò gẹ́gẹ́ bí ohun-èlò ìkọ́ni máa ń jẹ́ kí ìkọ́ni ní àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá túbọ̀ bá ojú ayé mú. Iṣẹ́-ìwádìí yìí ti wá ojútùú sí àwọn ìṣòro tí ó gún wa ní kẹ́ṣẹ́ láti gùnlé irú iṣẹ́-ìwádìí yìí. Ìṣòro àìsí ohun-èlò ìkọ́ni tó jẹ mọ́ àwọn nǹkan ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá ní àrọ́wọ́tó àwọn olùkọ́ ti di ohun afiṣẹ́yìn bí eégún fiṣọ, torí iṣẹ́ ìwádìí yìí ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn nǹkan wọ̀nyí ń súyọ nínú àwọn fíìmù wa gbogbo. Bákan náà, ọ̀rọ̀ àìsí akéwì alohùn Yorùbá ní àrọ́wọ́tó olùkọ́ láti pè wá sí kíláàsì náà ti di ohun àná torí pé àgbéyẹ̀wò àwọn fíìmù tí a ti ṣe nínú iṣẹ́ yìí tí jẹ́ ká mọ̀ pé àwọn ewì alohùn inú fíìmù àgbéléwò Yorùbá wúlò fún àpẹẹrẹ ní kíláàsì Yorùbá, pàápàá jùlọ ní ilé-ẹ̀kọ́ girama. Iṣẹ́ ìwádìí yìí tún ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àìní ifẹ́ sí wíwo fíìmù àgbéléwò Yorùbá kì í ṣe ìṣòro mọ́, bí a bá ti lọ̀ àwọn fíìmù náà mọ́ ìkọ́ni lọ́rùn, àti pé dandan ni kí ifẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ó jinlẹ̀ fún kíkọ́ àṣà àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, nígbà tí a bá ti lo ohun-èlò ìkọ́ni tí ó ní àkóónú ìdárayá.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Adébìyí, Adékẹ́mi (2012) "Ìfẹ̀sẹ̀lénà àti Ìdàgbàsókè Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá" nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Abẹ́òkúta: Federal College of Education, Abẹ́òkúta.

Adágbádá, O. (2014): ''Contemporary Women's Voice In Yorùbá Film Industry'' nínú

Research in African Languages and Linguistics(Vol 13), o.i 15-26.

Adéjùmọ̀, A. (2009):''Technologizing Oral Texts: Archiving Yorùbá Oral Literature through New Technology''. *LUMINA* 20(2), o.i 1-16.

Adélékè, D.A. àti Adébìyí, K. (2003): *Ọgbọ́n Ìṣèwádìí Ní Èdè Yorùbá.* Ìbàrà-Abẹ́òkúta: Visual Resources Publishers.

Adéoyè, A.A. (2003): *Ìtọpinpin Orírun, Àṣà, Pẹ̀lú Àgbéyẹ̀wò Àwọn Ohun Ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá*. Ọ̀yọ́: Immaculate-City Publishers.

Adéoyè, C.L. (1979): *Àṣà Àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Adéyínká, A.A. ''Ìwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ TEE 335: Ọgbọ́n Ìkọ́ni ní Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá''. Teacher Education Department, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Adú, Olúbùnmi (2012) "Ìfáàrà sí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá" nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Abẹ́òkútá: Federal College of Education, Abẹ́òkúta.

Àkànlé, A.O. (1992): "Ọgbọ́n Ìkọ́ni ní Èdè Yorùbá'' nínú Olú-Adérónmú, W.O., Ògúnbáyọ̀,


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

F.O àti Ikúdáyìsí, T.O. 1992. (Nigeria Certificate in Education Series-Yorùbá), Òǹdó State College of Education, Ìkẹ́rẹ́-Èkìtì.

Àrẹ̀mú, Fọlákẹ́ B. (2001): "Àwọn Àṣà Yorùbá tó jẹ mọ́ Ìbágbépọ̀, Ayẹyẹ àti Ohun-ìní'' nínú Adébáyọ̀ Ayéláàgbé (Olótùú) Àkójọpọ̀ Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá. Apa Kẹta. Ọ̀yọ́: Andrian Publication Series, Oyo State College of Education. Ọ̀yọ́

Babalọlá, A. (1966): *The Content and Form of Yorùbá Ìjálá*. Oxford: Clarendon Press.

Babalọlá, A. (1984): *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Babalọlá, A. (1991): *Ìwé Ìmọ̀dọ̀tun Yorùbá SS1*. Nigeria; Longman.

Dáramọ́lá, O. àti Jéjé, A. (1975): *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: Onibonoje Press and Book Industries. Nigeria Ltd.

Edgar A & Sedgwick P. (2002): *Cultural theory: the key thinkers*. London: Routeledge.

Fáléti, A. (1972): *Baṣọ̀run Gáà*. Ìbàdàn: Onibonoje.

Habib M.A.R. (2005): *Modern Literary Criticism and Theory, A History*. United Kingdom: BlackWell Publishing.

Haynes, J. àti Okome, O. (1997): ''Evolving Popular Media: Nigeria Video Films''. In Nigeria Video Films, Jonathan Haynes (Ed.), Ìbàdàn: Kraft Book Ltd And Jos: Nigeria Film Corporation 21-44.

Ikúdáyisi, T. O. (1992) "Ìtọ́wò Lítíréṣọ̀ Yorùbá" nínú Olú-Adérónmú, W.O., Ògúnbáyọ̀,

F.O àti Ikúdáyìsí, T.O. 1992. (Nigeria Certificate in Education Series-Yorùbá), Òǹdó State College of Education, Ìkẹ́rẹ́-Èkìtì.

Ilésanmí, T.M. (2004): *Yorùbá Orature and Literature*: A Cultural Analysis. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Ltd, Nigeria.

Lewis,M. (2012): Fourcultures: cultural theory and society. Available at http://fourcultures.com/2012/06/16/success-is-always-rationalised-says-michael-lewis/

NERDC (2009) Junior Secondary School Curriculum-Yorùbá (JSS 1-3). Sheda: Abuja.

NERDC (2009) Senior Secondary School Curriculum-Yorùbá (SSS 1-3). Sheda: Abuja.

Ògúbọ̀wálé, P.O. (1971): *Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ògúndèjì, P.A. (1991): *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. Ìbàdàn: University Of Ìbàdàn Centre For External Studies.

Ògúndèjì, P.A. (1992): *Yorùbá Drama I*. Ìbàdàn; University Of Ìbàdàn Centre For External Studies.

Ògúndèjì, P.A. (2014): ''Yorùbá Drama In Time Perspectives''. An Inaugural Lecture Delivered at The University Of Ìbàdàn.

Orímóògùnjẹ́ (1996): *Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá*. Lagos: Káróńwí Nigeria Enterprises.

Owólabí, O., Olúnládé, T. Adéránti, B àti Ọlábímtán, A. (1985): *Ìjìnlẹ̀ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá Ìwé Kìn-Ín-Ní*. Ìbàdàn: Evans.

Oyèrìndé, O. àti Alimi, K. (2011): *Àkànlò-Èdè Ayàwòrán nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá, Máyàmí fún Olùkọ́ àti Akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá*. Ìbàdàn: Standout Publications.

Ọmọlọlá, S.O. (2013): ''The Study Of Oral Tradition in Yorùbá Movies''. Ìwé Àkànṣe fún Oyè Ph.D ní Ẹ̀ka-Ìmọ̀ Èdè Ilẹ̀ Adúláwọ̀ ti Yunifásítì South Africa.


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY